# FIFI JESU HAN ATI IWADI ẸjỌ Ẹ̀ LỌNA EKE

## Maatteu 26:47-68; 27:1, 2, 11-26

### ẸKỌ 63 – FUN AGBA

**Akọsori: "A jẹ ẹ ni iyà, a si pọ́n ọ loju, ṣugbọn on kò yà ẹnu rẹ; a mu u wá bi ọdọ-agutan fun pipa, ati bi agutan ti o yadi niwaju olurẹ́run rẹ̀, bẽni ko yà ẹnu rẹ̀" (Isaiah 53:5).**

**I A Mu Jesu ni Ọganjọ Oru**

1 A rán ọpọlọpọ eniyan pẹlu ida ati ọ́gọ lati mú Jesu, Matteu 26:47
2. Judasi fi Jesu hàn pẹlu ifiẹnu ko ẹnu, Matteu 26:48-50; Johannu 18:10

**II Iwadi Ẹjọ Jesu Lọganjọ Oru ati Lowurọ niwaju Igbimọ awọn Ju**

1. Iwadi ẹjọ Jesu lẹẹkinni niwaju Kaiafa jẹ nbi oru, Matteu 26:57-668
2. A ṣe iwadi ẹjọ Jesu lẹẹkeji niwaju Kiafa ni afẹmọjumọ, Matteu 27:1; Marku 15:1; Luku 22:66-71

**III Iwadi Ẹjọ Jesu Lẹẹmeta niwaju awọn Onidajọ ti Romu**

3. Ẹri kinni ti Pilatu jẹ ni pe Emi kò ri ẹṣẹ lọwọ ọkunrin yi," Matteu 27:11, 2, 11-14; Luku 23:1-5
4. Hẹrọdu ri I pe Jesu kò ṣe ohun kan ti o yẹ si ikú, Luku 23:6-11, 15
5. Nigba ti a mú Jesu wá siwaju Pilatu lẹẹkeji, o wá ọna lati da A silẹ, Matteu 27:15-23; Luku 23; 13-20; Johannu8 19:12
6. Ariwo ọpWọ̀ eniyan bori, Matteu 27:24-26

## ALAYE

**Eto**

Ọjọ meji ṣaaju Ajọ Irekọja, awọn olori alufa ati awọn akowe pelu awọn agbaagba pejọ pọ̀ ni aafin Kaiafa, olori alufa, lati ṣeto bi wọn yoo ti ṣe pa Jesu lai rú ibinu awọn eniyan soke. Kò pẹ lẹhin eyim ni Judasi lọ gbimọ̀ pẹlu awọn olori alufa, o si gbà lati fi Kristi han fun ọgbọ̀n owó fadaka gẹgẹ bi Sekariah ti sọ tẹlẹ pe: "Mo si wi fun wọn pe, Bi o ba dara li oju nyin, ẹ fun mi ni owo-ọ̀ya mi: bi bẽkọ, ẹ jọwọ rẹ, Bẽni nwọn wọ̀n ọgbọ̀n owo fadaka fun iye mi" (Sekariah 11:12). Lati igba naa lọ ni Judasi ti n foju sọna fun akoko ti o wọ̀. Ni alẹ ọjọ Ajọ Irekọja naa. Jesu wà mikan pẹlu awọn ọmọ-ẹhin Rẹ̀ mejila. Akoko ti o wọ̀ fun Judasi ni yi. Kristi sọ fun un pe oun ni yoo fi Oluwa rẹ han, ṣugbọn eyi kò da a lẹkun. Judasi ṣaaju ọpọ eniyan pẹlu ohun ija lati ọdọ awọn olori alufa, o wi pe, "Alafia, Olukọni," o si fi ẹnu ko Jesu lẹnu.

**Iwadi Ẹjọ Lẹẹkinni**

Bi o tilẹ jẹ pe oru ni, sibẹ awọn akọwo ati awọn agbaagba pejọ pọ lati gbero bi wọn o ti ṣe pa Jesu Dajudaju, awọn eniyan wọnyi ti tó niye lati ṣe ipade igbimọ̀ tabi ti awọn Sanhedrin, eyi ti I ṣe ile-ẹjọ ti o ga ju ti a wọn Ju. Ko tọ́ fun igbimọ yi lati pejọ ni oru, ṣugbọn wọn joko lati ṣe idajọ Ọkunrin naa ti wọn ti ditẹ si. Niwọn bi wọn ti ni ọkan buburu si Kristi, ko tọ fun wọn lati jẹ̀ onidajọ lati wadi ọran Rẹ̀. O fẹrẹ jẹ ohun gbogbo ti igbimọ yi ṣe lati wadi ọran Jesu ni o lodi si ofin atọwọdọwọ wọn.

Wọn wá awọn ẹlẹri eke nipa eyi ti wọn I ba fi Jesu sùn niwaju ile-ẹjọ, ṣugbọn o ṣoro lati ri ẹni meji ti ẹri wọn dọgba. Nikẹhin li awọn ẹlẹri eke meji wá. Nwọn wipe Ọkunrin yi wipe, Emi le wó tẹmpili Ọlọrun, emi o si kọ́ ọ ni ijọ mẹta" (Matteu 26:60, 62); "Ati ninu eyi nã pẹlu, ohun wọn kò ṣọkan" (Marku 14:59). Niwọn bi awọn ẹni meji wọnyi ko ti le sọ ohun kan naa, ẹri wọn kò jaamọ́ nkankan gẹgẹ bi Ofin. "Li ẹnu ẹlẹri meji, tabi ẹlẹri mẹta, li a o pa ẹniti o yẹ si ikú; ṣugbọn li ẹnu ẹlẹri kan, a ki yio pa a" Deuteronomi 17:6).

Jesu gbọ́ ti awọn wọnyi n fi ẹsùn èké sun Un, ṣugbọn Oun ko sọ ọ̀rọ kan lati gba ara Rẹ̀ silẹ. A jẹ ẹ ni iyà a si pọ́n loju, ṣugbọn on kò yà ẹnu rẹ̀: a mu u wá bi ọdọ-agutan fun pipa, ati bi agutan ti o yadi niwaju olurẹ́run rẹ̀, bẽni ko ya ẹnu rẹ̀:7).

Ofin Igbimọ awọn Ju ko gbà ẹnikẹni ninu wọn laye lati jẹ olufisun. Ṣugbọn alakoso wọn ti I ṣe olori alufa fi Jesu sùn pe, "Mo fi Ọlọrun alãye fi ọ bu pe, ki iwọ ki o sọ fun wa bi iwọ ba ṣe Kristi, Ọmọ Ọlọrun" (Matteu 26:63). Bi a si ti fi I sabẹ ibura bayi, Kristi dahun, o si wi pe, Iwọ wii." Idahun Jesu gẹgẹ bi Marku ti kọ silẹ ni pè, "Emi ni." Gẹgẹ ofin awọn Ju, ọkan ninu awọn onidajọ wọn gbọdọ ja fun arúfin; onidajọ yi ni lati wi pe ko jẹbi. Bi gbogbo eniyan ba sọ pe arufin kan jẹbi ninu ọran nla, o ni lati jẹ pe idajọ ti a ṣe nibẹ ko le duro, nitori kò si ẹni ti o gbeja rẹ. Nitori bẹẹ, iwadi einbni kò le duro nitori pe, lọna kinni, gbogbo igbimọ ile-ẹjọ ni o sọ pe O jẹbi; lọna keji, ọrọ awọn kò dọgba nipa Rẹ̀; lọna kẹta; ọ̀rọ odi si Ọlọrun ti a fi I sun si ko lẹsẹ nilpe Oun tikara rweọ jẹri pe Ọmọ Ọlọrun ni Oun I ṣe, a kò si wadi rẹ bi otitọ ni Oun i se Messia naa tabi bẹẹ kọ́.

**Iwadi Lẹẹkeji**

Nini ọràn nlá, ti o ofin ni pe ki a to ṣe idajọ ikú fun ẹni kan a ni lati wadi ẹjọ rẹ wò lẹẹmeji. A ni lati fi odidi ọjọ kan silẹ laarin akoko iwadi wọnyi. Bi ẹni pe wọn n pa ofin mọ́, awọn igbimọ̀ yi duro titi di owurọ fun iwadi ẹjọ lẹẹkeji. Ko si ẹlẹri ti wọn gbọ́ ọrọ lẹnu rẹ, igbimọ ile-ẹjọ yi si tun rú ofin nipa sisọ fun Jesu pe ki O wá jẹri gbe ara

rẹ̀. Ko si ọkan ninu awọn onidajọ ti o gbeja Rẹ̀. Idajọ ti wọn ṣe pe O jẹbi yi ko lẹsẹ nilẹ, nitori pe gbogbo wọn ni o pamọ́ pọ lai si ẹni ti o gbeja Rẹ̀. Dipo ki wọn da A silẹ, wọn ṣe idajọ ikú fun Jesu nitori wọn ti da A lẹbi pe O sọ̀rọ odi si Ọlọrun.

I ba ṣe pe awọn igbimọ Ju naa ni aṣẹ ni akoko yi ni, lati mú idajọ iku yi ṣẹ, dajudaju wọn I ba ti sọ Jesu lokuta lẹsẹkẹsẹ. Ijọba Romu fi ile-ẹjọ awọn Ju silẹ klati maa ṣe gẹgẹ bi ofin ilú ati ẹsin wọn ti wi, ṣugbọn ọran ẹjọ ti o gba pe ki a pa eniyan tabi ki a da A silẹ, ni wọn gbọdọ mu wá si ile-ẹjọ ijọba Romu. Ile-ẹjọ awọn Ju ti ṣe idajọ, o si ti dá ẹjọ ti ko ni ẹtọ lati ṣe tabi lati mu ṣẹ. Ohun ti igbimọ ni lati ṣe ninu ọràn yi lai ṣe tayọ aṣẹ ti a fun wọn ni9 pe ki wọn mú ẹsun naa wá si ile-ẹjọ ijọba Romu.

**Ninu Itimọle**

Nigba ti O wà nini ihamọ ti igbimọ awọn Ju, o yẹ ki wọn ṣe Jesu pẹlẹpẹlẹ nibẹ; ṣugbọn dipo eyi, wọn huwa abuku si I -- wọn tutọ́ si I lara, wọn lù U. Wọn tun bu ẹtẹ lu ile-ẹjọ ti o ga ju lọ ni orilẹ-ede awọn Ju nipa irú iwa-ikà bayi. Isaiah ti sọ asọtẹlẹ nipa iru iwà yi: “Mo fi ẹ̀hin mi fun awọn aluni, ati ẹ́rekẹ mi fun awọn ti ntú irun; emi kò pa oju mi mọ́ kuro ninu itutọ si” (Isaiah 50:6). A maa n tọka si Agbelebu nigbakugba, gẹgẹ bi apẹẹrẹ ijiya Kristi fun wa, ṣugbọn ọpọ ni9 iya ti O ti jẹ ki O to de ori igi Agbelebu. “a ṣá li ọgbẹ nitori irekọja wa, a pa a li ara nitori aiṣedẽde wa, ina allia wa wà lara rẹ̀, ati nipa ina rẹ̀ li a fi mu wa lara da” (Isaiah 53:5).

**Niwaju Pilatu**

Lẹhin ti igbimọ̀ awọn Ju ti da Jesu lẹbi iku nitori ọrọ odi ti wọn wi pe O sọ, wọn de E, wọn si mu Un wá siwaju Pilatu, baalẹ ijọba Romu. Ohun ti Pilati sọ si Jesu fi han bi iwadi ẹjọ ti awọn igbimọ naa ṣe ti labuku to. Wọn pa idajọ ti wọn ti ṣe pe O jẹbi ọrọ odi ti sapa kan patapata. Wọn fi Jesu sun pe O ṣọtẹ si ijọba Romu. Eyi yoo mu ki Pilatu feti si ti wọn, ṣugbọn ọ̀rọ odi kò le ta ni eti rẹ nitori pe ọrọ odi ki I ṣe rirú ofin Romu. Nwọn si rẹ̀rẹ si I fi I sun, wipe, Awa ri ọkunrin yi o nyi orilẹ-ede wa li ọ̀kan pada, o si nda wọn lẹkun lati san owode fun Kesari, o wipe on tikara-on ni Kristi Ọba” (Luku 23:2). Iwa eke ti o buru ju lọ ni eyi nitori awọn ọrọ Jesu ni pe, “Njẹ ẹ fi ohun ti iṣe ti Kesari fun Kesari” (Matteu 22:21). Pilatu tú ẹjọ naa ká lakọkọ pẹlu ọ̀rọ yi pe, “Emi kò ri ẹṣẹ lọdwọ ọkunrin yi” (Lu8ku 23:4).

**Niwaju Hẹrọdu.**

Nigba ti Pilatu gbọ pe Jesu wá lati Galili, ti o wà labẹ akoso Herọdu, Pilatu rán Jesu si i. Niwaju Herọdu “awọn olori alufa ati awọn akọwe duro, wọn si nfi I sù gidigidi” (Luku 23:10); ṣugbọn Herọdu kò ri ẹ̀ṣẹ kan lọwọ Jesu. Bi o tilẹ jẹ pe a sọ wi pe Jesu ko jẹbi, Herọdu ti on ti awọn ọmọ-ogun rẹ, nwọn kẹgan rẹ, nwọn si nfi I ṣẹsin, nwọn wọ̀ ọ li aṣọ daradara, o si rán a pada tọ̀ Pilatu lọ’ (Luku 23:11). Eyi ni igba keji ti a dá Kristi lare ni ile-ẹjo ijọba Romu.

**Niwaju Pilatu Lẹẹkeji**

“Nigbati Pilatu si ti pè awọn olori alufa ati awọn olori ati awọn enia jọ, o sọ fun wọn pe, Ẹnyin mu ọkunrin yi tọ̀ mi wá, bi ẹniti o npa awọn enia li ọkan dà si kiyesi I, emi wadi ẹjọ rẹ̀ niwaju nyin, emi ko si ri ẹ̀ṣẹ lọwọ ọkunrinyi, ni gbogbo nkan wọnyi ti ẹnyin fi I sun si: Ati Hẹrọdu pẹlu: o sá ran a pada tọ̀ wa wá si kiyesi I, ohun kan ti o yẹ si a ko ṣe si I lati ọwọ́ rẹ̀ wá. Njẹ emi o nà a emi o si jọwọ rẹ̀ lọwọ lọ” (Luku 23:16). Pẹlu ọrọ wọnyi ni Pilatu fi wi ni igba keji pe “Ko jẹbi.”

I ba ṣe pe Pilatu jẹ ẹni ti n sọrọ ti o si n mu un ṣe, oun I ba duro gbọnin pẹlu ohun ti o mọ pe o tọna, ki o si dá Jesu silẹ. Dipo eyi), ariwo ọ̀pọ eniyan bori. “Pilatu si fi9 aṣẹ si I pe, ki o ri bi nwọn ti nfẹ” (Lu8ku 23:24). Ni ṣiṣe bẹẹ, Pilatu ba owe rere ti ofin Romu jẹ, eyi ti o wi pe: “A ki I ka ariwo ilu si, nigbati nwọn ba nfẹ́ ki a da ẹlẹbi lare tabi alare lẹbi.”

Ṣugbọn ohun ti o buru ju rirú ofin awọn Ju ati ti awọn aráRomu ni pe Pilatu rú Ofin Ọrun lai ṣe idajọ ittọ fun Ẹni to oun ti jẹri Rẹ̀ pe, Emi ko ri ẹ̀ṣẹ kan lọwọ rẹ̀” (Johannu 18:38), ati nipa fifi I lè awọn ọtá Rẹ̀ lọwọ lati kan An mọ agbelebu, nitori o bẹru ibunú eniyan ju ibinu eniyan nu ibinu Ọlọrun lọ. Bayi ni a mú Iwe Mimọ́ ṣẹ ti o wi pe: “Awọn oba aiy6e kẹsẹ jọ, ati awọn ijoye ngbimọ pọ̀ si OLUWA, ati si Ẹni-ọmọ rẹ̀ (Orin Dafidi 2:2).

## AWỌN IBEERE

1. Sọ awọn ọna diẹ ti iwadi ẹjọ Jesu ko fi ba ofin mu.
2. Tani ké eti ọmọ-ọdọ olori alufa kuro?
3. Awọn asọtẹlẹ ti inú Majẹmu Laelae wo ni a mu ṣẹ ninu ẹ̀kọ yi?
4. Darukọ oriṣiriṣI awọn oloye ijọba ti a mú Jesu tọ́ lọ.
5. Akpa ilú wo ni o wà labẹ akoko Pilatu?
6. Hẹrọdu mẹrin ni a dadukọ ninu Majẹmu Titun. Kin ni ohun miran ti a sọ nipa Hẹrọdu yi? Nibo ni agbegbè ti rẹ?
7. Ẹbi wo ni Igbimọ awọn Ju dá fun Jesu?
8. Kin ni awọn ẹsùn ti a fi Jesu sun niwaju Pilatu?
9. Njẹ Pilatu da Jesu lẹbi?
10. Eeṣe ti Pilatu fi jẹ ki a kan Jesu mọ agbelebu?